# OMI OKUN GBE WOLI ALADURA LO ATI ENIA MEJI

Drink Coca-Cola
STANDARD SIZE 4D · NEW KING SIZE 6D
SEE YOU PAY THE CORRECT PRICE.

ELETI OFE
A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO

CRAIGS
AWOGBA Omodi fun Giri, Eyi, Hihu-ehin, Orere, Ra Tire Ni Ile Egbogi — ISE — Olodumare Okebola, Ibadan. 116, Great Bridge St LAGOS

VOL. No. IX 512. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, MARCH 23, 1957 KỌBỌ MEJI (2d

## Omi Okun Gbe Woli Aladura Lo

Irohin kan wa wipe, Woli Aladara kan riran wipe ki on lọ gbawẹ ọjọ meta ni Okun Alasia. Nigbati Woli na nlọ, awọn obinrin Aladura meji fi ara wọn jin lati ba Woli na lọ ṣe ọjọ meje ni Okun Alasia na. Nwọn mura, a tilẹ gbọ pe obinrin Hausa kan wa ninu wọn ti o ba wọn lọ gbawẹ ni eti Okun na.

Gẹrẹ ti woli Aladura yi pẹlu awọn obinrin Aladura na bọ s'oju ọna ti nwọn lọ si okun, bẹni Woli miran ti o jẹ Aladura bakanna ri iran wipe woli Bayi-bayi nlọ si okun lati gbawẹ bi o ba wẹ lọhun, ko ni pada wa sile.

Bi woli ara Musbin ti ri iran yi tan bẹni o gbe onişẹ dide lẹsẹkanna, o si fun onişẹ na ni owo mọto wipe, ki o sare lọ ba Woli bayi-bayi ni eti okun, ki o si wi fun pe, ko gbọdọ wẹ ninu okun. Iranşẹ na si lọ o jişẹ fun woli ti o lọ gbawẹ na.

Gẹrẹ ti iranşẹ na jişẹ yi tan ni woli na ti o lọ gbawẹ ba bora silẹ pẹlu awọn obinrin meji ti o ba lọ. Nigbati nwọn de inu okun ti igbi mbọ, o ni ki

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited

Incorporated in Nigeria in 1933
Paid up Capital – £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria.
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS, NIGERIA
22 Branches throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO, BENIN-CITY, WARRI, SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS.
LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell
Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams: Natbaniger, London.
Head Office Representative in London
Ernest Olubunmi Obasa—Porter
CORRESPONDENTS
NEW YORK PARIS HAMBURG



## Mbu ba won se Ominira ile Ghana

Gegebi nwon ti se ominira fun ile Aganyin (Ghana) ni Gold Coast, bakanna ni nwon se ominira fun won nilu Oyinbo, ninu ile isin kan ti a npe ni (Martins-in-the-field) Eni ti a nwo aworan re yi wa ninu awon ti o lo sibi isin idupe na Matthew Mbu, Lennox Boyd, R. A. Butler, Duke of Gloucester, Hugh Gaitskell Archbishop of Canterbury ati opo awon Gbajumo nilu Oyinbo.

## OLORI OLOJO BA ALADURA DIJE

Ọkunrin kan ara Şaki lo kọwe yi pe, on gẹgẹbi olori awọn afa'jo, on ti ngburo ẹniti o le fa ojo şugbọn on ko ri ẹniti o le fi ara we on.

Bi on ba fa'jo, ko si ẹni i o le fo o, bi on ba si ba ojo, ko si ẹni ti o le fa a. Ati pẹlu pe bi on ba fa ojo, apa ibiti on ba fẹ ki o rọ si, ni yio rọ si.

Lẹhin na, olori kan ni on jẹ ninu awọn Mogba. Nisisiyi bi o ba di ni ọjọ Saturday June 29, on pẹlu Olori Olojo kan ni agbegbe ilẹ Eko jijọ şeleri fun ọjọ na.

Olojo na sọ fun on pe Aladura ni on, ọjọ na si jẹ ọjọ ti awọn yio şe ajọdun, o wipe, bi nwọn ba gbọ pa! ki nwọn mọ pe nşe ni ojo kan, şugbọn emi Olori Olojo şeleri pe 29th oşu June yio jẹ ọjọ ti ojo yio rọ nilu Eko lati owuro di alẹ. Bi ko ba ri bẹ ngo di ọkan ninu awọn Aladura.

## U.A.C. Chairman In Lagos

Mr. A. H. Smith, Chairman of the United Africa Company Limited, London, is paying a short visit to Nigeria on his way to the Belgian Congo from Ghana where he has been representing his Company at the Independence Celebrations.

Mr. Smith has been promoted Officer of the Legion D'Honneur.

# Ghana Celebration

U. K. FIRM 'PARCELS OUT'

Ghana's arrangements for last week's National Independence Day celebrations, it is now revealed, were so elaborate that not only the equipments but also some top "Know-hows of a huge British concern were "parcelled out" for the additional electricity used at Accra on that historic occassion.

The two new engines roared into life for the first time on March 6, when Ghana's independence was formally declared.

The engines, which have since inreased Accra's electricity output by more than half, were shipped to Ghana by a member of the world-famous British Brush Group—Mirrlees Bickerton & Day Ltd of Stockport. Both the Engineer specially flown over to Accra to supervise the installation and switch-on, as well as the new permanent representative of the Group in Ghana, Mr. K. A. M. Potter, came from the Group.

Ghana and the Brush have been friends since 1913 the Group being in fact one of the largest British suppliers of equipment to the Country for over forty years. Two of their factories have supplied equipments to other power stations in Accra, Cape Coast, Kumasi, Swedru, and the Weija waterworks.

# P. W. D. Gbarada

Awọn oyinbo ti o nṣe Ọlotu ile iṣe ilu Public Works Department ranṣẹ pe gbogbo awọn Oniwe Irohin lati fi iṣẹ ti nwọn nṣe ati eyiti nwọn ti ṣe han. Ọlọla Inua Wada, lo kọkọ ba awọn Oniwe Irohin sọrọ, gẹgẹbi o ti jẹ ifẹ inu on ni wipe ki ilu Ẹko ni ilọsiwaju.

Lẹhin ti nwọn kuro nibẹ, nwọn lọ si Exhibition Centre, nibẹ ni nwọn gbe fi orisi-risi ẹrọ ti nwọn ni lọwọ lati fi ṣe iṣẹ-kiṣẹ ti o ba kan lati ṣe. Nigbati nwọn kuro nibẹ, nwọn lọ wo ibiti P.W.D gbe nfi ẹrọ la igi ni ebute Ijọra ati bi o ti jẹ wipe, gbogbo awọn ohun ọṣọ ile ti awọn onisẹ ijọba ma nlo, P.W.D. l'o nṣe. Lẹhin eyi ni nkan ipa'nu bẹrẹ.

Nigbati wọn kuro ni Ijọra, nwọn tun kọri si odo Ogun. Ibiti odo Ogun na wa to buso mẹfa si Agege nwọn fi awọn ẹrọ ti o nfa omi lati inu odo ogun han wọn. Nwọn sọ pe awọn ẹrọ ti o nfa omi odo Ogun nfa garawa 25,000 ni wakati kan, eyi jẹ 100,000 gals. Tank nla nibiti omi ngba wa si Eko gba 9,000, 000 gals omi, ọpọlọpọ omi na ni a nmu lọsan ọjọ kan, eyiti a nmu loru ko to nkan. Omi ọna meji ni a nmu l'Eko. Omi lati odo Iju ati omi lati odo Ogun

Gbogbo mọto ti P.W D. ni pata-pata le ni 2, 600, awọn mọto titun ti nwọn ni jẹ 116. Awọn ti nwọn ṣẹṣẹ tunṣe tan jẹ 195. Lẹhin ti nwọn ti mu wọn kari gbogbo rẹ tan, ni nwọn tun ko nkan ipa'nu silẹ. Jọwọ awe ! iṣẹ kekere kọ ni awọn P.W.D. nṣe o.

# Bi emi tile na temi niyi

OLOTU,

Gẹgẹbi Ọgbẹni E. A. Adekẹyẹ ti sọ pe on fẹ ki mba wọn na owo na, nitoripe on ri oye pe ko si ẹni ti o le mọ owo na ni nina.

Emi yio ra mọto

| | |
|---|---|
| Pontiac kan | £1,000 |
| Ẹrọ ti nwọn fi nroko | 5,000 |
| Awọn ohun ilo iroko | 1,000 |
| Ọkọ oju omi | 500 |
| Ẹrọ to npa ekurọ | 500 |
| Mọto ti nko ẹru | 800 |
| Mọto ẹlẹsẹ mẹta | 200 |
| Ngo na ilẹ fun kikọle | 200 |
| Simẹnti | 200 |
| Yanrin | 100 |
| Okuta wẹwẹ | 100 |
| Patako | 100 |
| Owo awọn Brikila | 1500 |
| Owo awọn Kapinta | 1500 |
| Owo awọn Lebira | 1500 |
| Owo awọn Headmen | 1500 |
| Owo Contractor | 4300 |
| | 20,000 |

Emi ni Nawo-nawo ẸSỌ


## Kere o!

A ti ni orisirisi ogun Germany to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS
MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos





**E L E T I Ọ F E**
A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJỌ
EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELGREAM
28, Kosoko Street, Lagos "ELETI - ỌFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23370
VOL. IX. NO 512, LAGOS, SATURDAY MARCH, 23. 1957

# Gbangba Dekun........

Kedere bẹwo, ni iṣipaya ọrọ ti Oloye Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ sọ ni ọjọ Jimọ ọsẹ to kọja wipe niti on ati ti ẹgbẹ Afẹnifẹre (*Action Group*) Iṣọkan gbogbo ile Nigeria ni ohun akọkọ ti o jẹ eto ti awọn yio ṣe. Ekeji nitl ijọba Ominira ti a nlepa rẹ, Oloye Awolọwọ sọ wipe niwọn igbati eto ijọba ominira ba ti ṣe fun ijọba Iwọ-Orun, iṣẹ on ni agbegbe na f'aratl nuni.

Lẹhin eyi ni Oloye Awolọwọ tun tẹsiwaju ṣe alaye wipe awọn ti mọ amọdaju wipe ijọba ominira ti agbegbe kan kole ṣe idiwọ fun ijọba apapọ ṣe, ati pe gẹgẹbi on ti ngba lero, bi awọn aṣiwaju yoku ba fi ifẹ si bẹ, ki awọn parapọ bere fun ijọba ominira fun gbogbo ilẹ Nigeria ninu ipade eto iṣ'elu ti awọn nlọ ṣe laipẹ yi, ki awọn si fi siwaju Alaiyeluwa ọba ilu Oyinbo Gẹsi wipe ki nwọn o ṣe lyọnda ijọba ominira fun ilẹ Nigeria ati pe ki ile igbimọ apapọ nla (House of Representatives) ni Alakoso ijọba (Prime Minister) ti yio mu opo ijọba Nigeria dani.

Eyi jẹ ọrọ pataki ti Oloye Ọlọla Awolọwọ fi p'ana eke ati agbọsọ ọrọ mọ awọn agbode-gba enia lẹnu, o si fihan wipe on ko si ninu ijọ-ti-ararẹ-l'omọ, ti awọn aturọta-bi-elubọ nsọ kiri wipe ijọba Iwọ-Orun nikan ni ẹgbẹ Afẹnifẹre wa fun. Ọrọ ko jẹ bẹ rara.

Ki awọn Alakoso ijọba yoku gba ọrọ yi yẹwo . O di ọwọ wọn.



## Awolowo

Ẹni ti a nwo ninu aworan yi ni Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ on lo gbalejo Sardauna Ṣokoto lọjọ Atalata 19th oṣu March 1957. Agbọ wipe, ohun ti Sardauna titori rẹ fo bi eiyẹ wa bẹ ilu Ibadan wo ni ọrọ isọkan ilẹ Nigeria.

Oloye Awolọwọ ti fi ọrọ iṣọkan yi lọ lasiko ti nwọn ṣẹṣẹ bọ lati igbimọ ti nwọn ṣe gbẹhin ni ilu Oyinbo. Ẹni ti a sọ fun wipe ki o ṣe to! ni igba kan, ti o si dahun pe, "Ẹ fi mi silẹ, nko le bọrọ ma ṣe To, To, To, bẹ gan ni ọrọ na ri.



# Dokita Azikiwe

Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Dokita Nnamdi Azikiwe, ti iṣe Alakoso Ijọba Ila-Orun, ti ọrọ iwadi wo nipa Banki rẹ d'ogun ti o d'ọdẹ, ti o fi tu ile igbimọ Ila-Orun ka lẹhin ti abọ iwadi na da lẹbi iwa aitọ gẹgẹbi ipo rẹ (Premier).

On ni ẹniti nwọn tun dibo yan pada sinu igbimọ lati tun di opo ijọba Ila-Orun mu fun ọdun marun.

Ọlọla Ahmadu, Sardauna Ṣokoto ti o dakan wa si Eko sọ wipe on yio foju kan Dokita Azikiwe nipa ajọsọ ọrọ awọn Ogunna-gbongbo mẹtẹta ki awọn to lọ silu Oyinbo fun eto ilu wa.

No. 42.

**Federal Government Scholarships Anb Bursaries, 1957-58**

Applicants for Federal Government Scholarships or Bursaries who may be waiting the result of examinations are hereby reminded that they are required to inform The Permanent Secretary, Ministry of Social Services, Lagos of the result of these examinations at as early a date as possible.



# E. O. Eyo Wo'le

Eniti a nwo aworan re yi ni Ogbeni E. O. Eyo omo ilu Uyo, on ni eniti o tako Dokita Azikiwe ninu iwadi oro Continental Banki, ti awon egbe N.C.N.C, se apero le lori pe ko ni wo igbimo mo, Ogbeni na Eyo ara Uyo ti a nwo aworan re lo w'ole sinu igbimo labe Ategun egbe Afenifere [Action Group] on ni Azikiwe fise Serekede (Chief whip) ninu igbimo (Assembly) ti atijo. On l'eniti o fa iwadi Continental Banki wo ti akara fi tu s'epo, ti o mu nwon tu ile igbimo Ila-Orun ka. "Okunrin funfun bi agbado"

# E Ma Polowo Oja Yin Sinu Iwe Irohin Eleti—Ofe

## E gbadura fun alafia Public Works

(O bere loju ewe kefa)

Nigbati nwon si ri wipe omi iju ko ni to awon ara Eko ni mimu, nwon tun fi ori la igbo lo de Odo Ogun, nitori nwon mo pe lori won ni emi awon ara Eko wa, opo enia lo kan ri omi tutu lofe-lofu, ti ko mo iru wahala ti awon Public Works Department ti se ki omi to di lilo lofe-lofu,

Eyi nikan ko, nigbati Ogun jle Yoruba buse ti awon igbimo Reluwe la'na lati Eko titi lo de ona Oke-Oya, iba ilu ti nwon ri pe yio se won l'anfani ni nwon se Reluwe de, sugbon P. W. D. lo la oju ona fun Moto lo si gbogbo ile Yoruba, Kemberi, Wukuwuku titi lo kan awon Filani,

Anfani ti ile wa nje labe igbimo P.W.D. ko se fi enu so. Nigbatj ljoba da igbimo Munisipa sile, ti awon ijoba roye wipe is'akoso yio poju fun igbimo P.W.D, ni nwon ba kuku gbe ise itoju ilu le igbimo Lagos Town Council lowo lati ma se akoso oju ona mo-to ti arin ilu Eko ati lati ma mu oju to ise omi ero nilu

Igbimo Public Works lo ti nse alakoso ise ina Lentiriki siwaju, Ki awon igbimo na to bere ise ina Lentiriki, Atupa onisedi ni nwon ntan nigba aiye Gomina Lugard, nwon npe awon ti o ntan ina na ni "Lampost" P.W. D. lo koko gbe ina Lentiriki de Eko.

Nko ni soro pupo, nitorina, e gbadura fun alafia Public works Dept.

## Omobinrin (girl guide) nlo silu oba

Larin osu Juy 29th si osu Aug 7th 1957 awon egbe ologun odomobinrin ti o mbe ni gbogbo agbaiye yio se ajodun kan nilu Oyinbo nibiti a npe ni windsor Great Park. Awon asoju yio wa lati India, Kaduna, Gold Coast, Nigeria, Sierra Leone, Australia Ceylon, Japan, Honkong ati orisirisi ilu miran,

Ninu ipade na, omobinrin meji lo nlo lati se asoju fun agbegbe Iwo-Orun, Nigeria. Oruko awon omobinrin meji ti o nlo na ni, Omidan Adekorede Lawal, ti o nse omo ilewe Queen School ni Ede ati Elizebeth Gascoyne, ti o nlo si ilewe St. Theresa nigboro Ibadan.

Awon omobinrin mejeji yio gunle silu London ninu osu July 22nd, nwon o lo ose kan ninu College of Westfield. Niwon ose kan tabi meji nwon o pada wale.

## Ọyaya dara pupo

Lati ọwọ
MODUPẸ ODUTỌLA

Ni ilu kan ni igba atijọ, ọdomọkunrin kan wa ti orukọ rẹ njẹ Abu. Iṣẹ biriki ni iṣẹ rẹ ni ṣiṣe.

On pẹlu ọdọmọkunrin ẹlẹgbẹ rẹ kan jijọ ndu ọmọ wundia kan; o si wa jẹ pe lọwọ Abu lo bọ si. Nipa bayi, eyi ọmọkunrin keji si lọ bẹ onişegun kan lati wa ba on pa Abu. Ni ọjọ ti wọn nlọ, o tẹle baba onişegun de adugbo awọn Abu, o si nawọ si ile rẹ fun.

Bi onişegun ti wọ abule, Iya Abu lọ ba, Abu wa ni ebute nibiti o gbe nşişẹ biriki rẹ, bi onişegun ti wọle ni Iya Abu bẹrẹsi ki mẹsanmẹwa, baba na si bere bi aye ba wa lati sun si, iya Abu si tẹni si iyara kan o gbe onjẹ sibẹ fun, o si bu omi si baluwẹ fun lati fi wẹ. Onişegun wẹ o si jẹun o yo. Iya Abu sure lọ si ebute o lọ pe ọmọ rẹ lati wa ki alejo wọn.

Abu wọle wa o si ki baba yi t'ọyaya-t'ọyaya, wọn si tun jijọ wi iregbe fun igba diẹ ki Abu to pada si ebute laimọ ẹmi-lẹmi pe tori t'on ni baba yi şe wa.

Nigbati ilẹ ọjọ keji mọ, baba onişegun pe Abu ati Iya rẹ pe on fẹ ba wọn sọrọ, o dupẹ lọwọ wọn gidigidi o si sọpe, ẹko mọ mi ri ti ẹ fi gba mi si ile yin, ti ẹ gba mi t'ọwọ t'ẹsẹ. Enia lo bẹmi l'ọwẹ wa si abule yi lati wa pa Abu ọmọ rẹ, sugbọn fun gbogbo ohun ti ẹ şe fun mi ko ni şe nkankan mọ, o si rohin bi ọdọmọkunrin keji na ti şe ati iye owo to gba lọwọ rẹ. Nigbati Abu ati iya rẹ gbọ, aiya wọn ja pupọ, ara wọn si gbọn rekọja.

Nigbana ni baba onişegun yi sọ fun Iya Abu pe bi o ti şe nşe tẹlẹri ni ki o ma şe, ki o ma yi iwa rẹ pada, Ọlọrun a si ma ti ẹ lẹhin. Nitori o ti fi iwa rere re gba emi ọmọ re sile ki o ma foiya, ohunkohun ko ni şe ọmọ re, nigbana ni baba onişegun dagbere fun wọn o si ba tirẹ lọ.

Itan yi kọ wa pe ki a ma şe ọyaya si gbogbo enia. Ẹlomiran a ma foju tirin enia ẹlomiran kẹ wa bi o tilẹ ki, ko ni da ẹ lohun tara, eyi ki işe iwa to dara rara o.

## Itan Bi Eran Ibiye Ti Se Di Owe

Nilu Abẹokuta, gbajumọ obinrin kan wa ti nwọn npe ni Ibiyẹ. Ibiyẹ si ni ẹran ewurẹ kan ti o fọju, nşe ni nwọn fi ẹran na ta a lọrẹ.

Ibiyẹ jẹ ẹniti gbogbo awọn enia fẹran, a si ma şe iranlọwọ pupọ fun awọn aladugbo rẹ, gbogbo enia lo nsa fun laifi Ibiyẹ.

Nigbati o şe aisan, şe tobẹ ti oju rẹ fọ, ko si le jade mọ, şugbọn ẹran ewurẹ Ibiyẹ yi buru de gongo, ko si nkan ti enia yio gbe silẹ ti ko ni tẹnu bọ. Bi nwọn ba le ti o si salọ, o tun npada bọwa. Nigbati nwọn ba le, le, le, ti o su wọn nigbana ni nwọn, o wipe, "Ki lo tilẹ şe ẹran Afọju yi" lẹhin ti ẹrọ yi ba ti bọ lẹnu wọn tan, nwọn o tun yara fi ọwọ bo ẹnu, nwọn o si wipe "Amuni buni eran wo niyi ẹwẹ"?.

Eyi na lo di owe bayi wipe, Amuni buni ni ẹran Ibiyẹ. Ibiyẹ fọju, ẹran re si fọju.

**Polowo Oja Re sinu Iwe Irohin Eleti - Ofe**

## Egbadura fun alafia Public Works

Ninu gbogbo awon ijoba ti o nse ile Nigeria, awon ti o ye ki a ma kara-kun ilosiwaju won ni igbimo Public Works Department. Idi re ti mo se wibe ni wipe, nwon je okan ninu awon olore ilu Eko ati nipataki olore fun ile Nigeria.

Lasiko igba kan ni a ti ma ngbo iru igbe bayi larin ilu Eko wipe "E karo, e karo, olomi d'ebute" Bi gbogbo enia ba ti gbo iru igbe yi, ni nwon o ma bere pe. "Ebute ibo?" o di witi, witi, olukuluku yio gbe garawa epo oyinbo lati lo ra omi tutu. Ko nse wipe, omi ko si ni Eko, o wa sugbon omi digbolokun ni a nmu nilu Eko, eyi lo jeki gbogbo enia ma jijadu lati lo ra omi tutu,

Sugbon awon igbimo Public Works tabi Oyinbo Alapako ni nwon npe won nigbana, lo fi ori lalighbo la iju ti nwon la'na titi lo de odo Iju.

(Wo yoku loju ewe karun)




**Awon ti o nya aworan feran Siga Capstan orun re dara.**

# Sarduna



Gbukẹ ni a ri ọlọla Sardauna Ṣokoto ti o dakan wa si Eko latì ba awọn olugbimọ rẹ sọrọ pọ nipa iṣẹ ijọba Oke-Ọya.

Ọlọla Sarduna yi sọ wipe on yio foju kan Oloye Awolọwọ ti iṣe Alakoso ijọba Iwọ-Orun gẹgẹbi imọran ti awọn enia mu jade wipe ki awọn ti o jẹ Alakoso ijọba ti Oke-Ọya Iwọ-Orun ati Ila-ọrun ṣe ipade pọ lati yanju edekoyede ti o ba wa larin awọn, ki awọn to lọ si ipade eto ilu Nigeria, nilu Oyinbo, ki ọrọ awọn mẹtẹta le jẹ ọkan pọ mọrawọn.

Atipe yio jẹ itẹlọrun fun on nibikibi ti nwọn ba fẹ ki awọn ṣe ipade na, bi wọn ba si re si ọdọ on, inu on yio dun lati gba wọn l'aleje towọ-tẹsẹ.

Gbere rẹ, Sarduna, ọmọ alahusa.

Ẹ WO AWAMỌTO ONIWAKUWA

THE FAULTY DRIVER




Tabi ẹ ko ri awamọto yi bi o ti nsa ere isakusa lọ loju Titi laibikita fun ẹmi ọmọ enia. Nigbati o de orita mẹrin nibiti o gbe ni lati duro wo ọtun ati osi kio to malọ, nṣe ni awamọto na kun kọja lọ bi mọna-mọna.

Bi o ti de itosi ilewe kan ni ibiti o gbe ni lati rọra ma rin, nṣe lo nkun kọja lọ. Ọmọ ilewe kan ti o sare kọja loju Titi, nṣe lo fi mọto tẹ ọmọ na apo iwe rẹ, fila ati ẹwu awọleke rẹ danu soju Titi.

Nibiti onimọto ndu ara rẹ ti o mbojuwo ẹhin wo ọmọ ti o ti fi mọto tẹ, ko ṣakiyesi wo iwaju bi mọto miran mbọ, nṣe lo kuku ralu mọto ti o mbọ, o si gbina. Ẹ ko ha ri aiye iwakuwa mọto bayi?

## IGBIMỌ EGUN - AWORI Ṣ'OFIN TITUN.

(O bẹrẹ loju ewe keji)

(g) Awọn to npatẹ ọja, ti ko ni isọ yio san tọrọtẹrọ ni gbogbo ọjọ ọja.

(h) Awọn ti ko ni isọ, ti ko si patẹ, ti nwọn ọkiri ọja tiwọn yio ma san kọbọ-kọbọ ni gbogbo ọjọ ọja.
Awọn oni mọto ero, tabi ti ẹru yio san 2/- ni gbogbo ọjọ ọja.



Lati ọwọ osi, Ọgbẹni Young, Oloye A. Obiṣẹsan ati Oloye C. D. Akran

# Igbimo Onikoko Fowo Si Ban' Enia Dudu

Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni Ọgbẹni Andrew H. Young, C.B.E. ti o nṣe Alaga fun Igbimọ Onikoko (Marketing Board) on l'o mu iwe owo (cheque adọta ọkẹ Poun dani lati fi ṣe ẹbun fun awọn igbimọ Western Cooperative Bank Ltd. Ẹniti o duro ni arin wọn ni Oloye A, Obiṣẹsan, ti o nṣe Alaga Igbimọ Cooperative Bank ati Oloye C.D, Akran ti o nṣe olotu fun ilọsiwaju ilẹ enia dudu (Minister of Local development)

E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Fun Irohin Aladun Ki E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Re

## AWO REKODU 6/-

Wa ra awọn rekọdu ti o gbadun nwọnyi lọdọ wa!

1870. E s i ọ r ọ nyin ; Lawani Akano – S. Aka.
1871. Omo atiro ; Olanrewaju — „
1872. Abanijẹ ; Bisiriyu Kayode — „
1876. Late Awoyele ; Daniel Oreyọmi – Ayinde Bakare.
1877. Late Omoṣola Savage ; Ọrẹ meji — „ „
1878. L.O. Gbamgbala ; Sule Mayeto — „ „
1884. A j ẹ m ọ g b e ; Moronmubọ – Rio Lindo
1885. Late Omoṣola ; Jo Mambo — „ „
1886. Olomo lo laiye ; Late Awoyẹle — „ „
1887. Sio lele ; Late Chief Thomas — „ „
1902. Oṣede Mbaje ; Ẹda ma tori awa da – Alabi Ewuro
1903. Igba mbajo ; Eleko Adisa. — „ „
1904. Gbi ni mo gbọ ; Erinmi lokun — „ „
1912. Aka ṣe mi lalejo ; Jubirila – Lamidi Ajeigbe
1913. Af'emi - af'emi ; Mo re mọ kan — „ „
1914. Ma mowo ra ; Kinkin n i mi — „ „
1915. Oba ile a i y e : Mapaja — — „ „

Fi owo - ọ k ọ kun o w o ọja ti o ba fẹ r a.

**Egba Trading Aradan Stores**
18, Denton Bridge Street,
P.O. Box 2, Ebutte Metta


## Oloye Akintola da imoran Ominira l'odunni



Ninu ile igbimo apapo nla ti Eko, ni olola oloye S. L. Akintola gbe oro ominira fun ile Nigeria dide wipe ki igbimo fi ase si wipe ki awon ti yio lo silu Oyinbo fun atunse eto ilu bere gidigidi fun ijoba ominira ile wa l'odunni.

Awon ijo egbe Alakuko (N.C.N.C.) ati ijo egbe olomi (N.P.C.) se atako wipe ki nwon fi ase si wipe ki awon ti yio lo silu Oyinbo bere fun ijoba ominira fun ile wa ni odun 1957 Awon ti o se atako na ni Olola S. A. Wachuku ati T. O. S. Benson (N.C.N.C.) ati Malam Yakubu Wanka ati Malam Maitama Sule (N.P.C.)

Eyi yio so asiko ijoba ominira ile wa di odun meta ki a to le danwo. Oro re o enyin enia wa.

### OMI OKUN GBE WOLI ALADURA

(O bẹrẹ loju ewe kini)

nwọn bẹrẹ, bi awọn si ti ṣe bẹ tan ati Woli ati awọn obinrin mejeji ti o ba lọ, nṣe ni okun gbe gbogbo wọn lọ. Ọmọ to ba kọ ibawi baba rẹ kẹgan Ẹlẹda rẹ.


**HINDU SANKARA'S**
**Religious Art Jewelleries**



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas. Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

*Enclose 4/- money order by Air Mail for Catalogues and Literature.*

HINDU SANKARA, 20 Montpelier Row, Blackheath, London, S.E.3, England



## "JOFABRO"

Awo Ikorin (RECORD) ti o ba ri Oruko "JOFABRO" Lara Re

L'o Dara Julo

Gbekele Awo Ikorin ti "JOFABRO" fun igbadun orin ile enia dudu.

Bi o ba fẹ Awo Ikọrin tabi a ni orin lati kọ.

wa so fun:
**Josy Ola. Fajimolu & Bros.**
**21, Balogun Street West, Lagos.**
**Phone 23856**

Eka ile ita'ja wa mbe ni gbogbo Nigeria.


No. 44.

## King George V Park Onikan

HOURS OF OPENING

Monday – Saturday : 9. 30 a.m. – 6. 45 p.m.
Thursday : 9. 30 a.m. – 9. 45 p.m.
Sunday : 2. 00 p.m. – 6. 45 p.m.

Attention is drawn to the evening hours of opening on Thursday when the exhibits can be seen under very favourable conditions.

CONTENTS.

The Museum contains three galleries:

(1) Traditional Art, Chiefly exceptionally fine wood-carvings from all parts of Nigeria.
(2) Archaeology, Metalwork and Terra Cottas among the exhibits is one of the famous heads from Ife and a life-size terra-cotta head from Nok, over 2000 years old.
(3) Ivories and Bronzes of Benin. Selected examples some of which date from the 15th century and nearly all of which were taken from Nigeria sixty years ago.






Iwe Irohin Eleti-Ọfe D'araba, E Ma Ka a.

Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company. 28, Kosoko Street P. O. Box 647 Lagos Phone 23370